## Kinișe ti a kori "Alọ o? Alọ!" ka mọ?

OJE idunnu fun awa ọmọde lati ma a fi alọ șe idaraya ninu iwe "Irohin Yoruba" lọsọọsẹ. Șugbọn o dun wa pupọ pe lati bi oșu diẹ sẹhin a ko ri ki alọ na ma a jade mọ. Kini idi rẹ ti ko fi jade mọ tabi ẹ ko fẹ gba alọ tẹ jade mọ ni? Olotu, ẹ jọwọ, ẹ la a ye wa o.

Mo dupẹ aye ti ẹ gba mi.

YAKUBU POPOỌLA.

Oshodi.

**AKIYESI—A ko da ẹnikẹni duro lati ma a fi alọ șọwọ șugbọn ohun ti ko jẹki a ma tẹ alọ jade nisisiyi ni wipe ọpọlọpọ alọ ti a ti pa sinu iwe ni nwọn tun nfa yọ ti nwọn tun npa șọwọ siwa. nitorina ẹnikẹni ti o ba ni alọ ti o jẹ akọtun ti kii șe iru eyiti a ti tẹ jade ri ki o pa a șọwọ a o si tẹ ẹ jade fun un.**

OLOTU.

# Iwe si Olotu Irohin Yoruba

## Awọn ọmọ ilu Ijabẹ dupẹ lọwọ Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre

EJỌWỌ gba mi laye lati fesi si ọrọ Ọgbẹni J. A. Abidoye, Ghana, ti o jade ni oju ewe keji iwe "Irohin Yoruba" ti 30.11.58 nipa pe ki awọn ọmọ ilu Ijabẹ jẹki irẹpọ wa larin wọn. A dupẹ pe irẹpọ tiwa larin awọn ara ilu Ijabẹ nisisiyi, iyipada rere si wa pẹlu lati igbati awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ti fi ẹsẹ rinlẹ ni ilu Ijabẹ, to bẹ ẹ ti awọn Ọgbẹni Emmanuel, Baba Ẹgbẹ Ẹka Alakukọ Ijabẹ; Francis Olawuyi, Akọwe Ẹgbẹ Ẹka Alakukọ Ijabẹ ati gbogbo enia ile wọn fi di ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group).

A si tun dupẹ lọwọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, fun ifẹ Yoruba ti o ni lọkan, ati lọwọ Oloye S. L. Akintọla, ati lọwọ Ọba Onijabẹ, ati lọwọ awọn Ọgbẹni Gabriel Afolabi, alaga ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ijabẹ, Samuel Ẹniọla, Baba Ẹgbẹ Ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre Esa Ijabẹ ati Shittu Ọlaoye lori wahala ikẹgbẹjo ati isẹ iṣelu Ijabẹ.

A tun dupẹ lọwọ ẹnyin ọmọ ilu Ijabẹ ti o wa ni Oke Okun (Ghana) ti ẹ fi ara mọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre, Oluwa k'o mu ẹsẹ nyin duro Awa ti mọ pe irọ ni Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) npa fun wa ti nwọn npe Ẹgbẹ Olomi (NPC) ni Ẹgbẹ Musulumi. Așiri nwọn ti tu nitori Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ko șe eto ișelu rere kan fun wa ri. Isẹ Onarebu ati Kansilọ ki ișe isẹ Anọbi, irun-kiki ni o sọ pe o le mu enia de ọrun rere, ki ișe ibo ti a ba di fun Ẹgbẹ Musulumi.

Emi ni,
S. A. LAWAL.

Ijabẹ.

## Ẹnyin Musulumi Onimimọ ẹ sọ si i?

OLOTU—Mo dupẹ lọwọ nyin pupọ lori ọrọ ẹsin ti Alfa Akewukewu pẹlu Baki Jumọ nșe alaye ti nwọn si nta ko ara wọn. Idi ti mo fi dupẹ lọwọ nyin ni pe, ẹ jẹki a ri alaye wọn na ka yekeyeke ati ni aseko. Ki Oluwa fi ibukun si inu isẹ rẹ ati ile rẹ titi lailai.

Mo fẹ ki gbogbo Imale agbaiye ti o ni imọ ijinlẹ nipa Islam, paapa awọn Alfa Oni Jalalaini Alalikuraini; Ansarud-Deen; Ahmadia ati awọn Ajẹșebi- ara -Mekka ati Alfa Bandele ni Ibadan șe alaye lori ọrọ esin na ti o jade ninu "Irohin Yoruba" ni ọjọ Aiku ti isẹ ọjọ keje oșu kejila ọdun ti o kọja yi.

Idi ti mo fi fẹ alaye wọn na ni lati mọ eyiti o to ti o si yẹ lati tẹle ninu ọrọ awọn mejeji. Mo si ni ireti pe alaye na yio kun dada, yio si ni ileri ọrọ Ọlọrun ninu Iwe Mimọ.

A dupẹ o.

Emi ni,
LIHADI LAWAL.

Iddo Ajinnare lẹba
Ilesa.

***Ẹ ma a ka Iwe IROHIN YORUBA nigbagbogbo fun irohin aladun***


# FIHAN pe pẹlu agbara idan ni Surf fi nfọ aṣọ mọ

**1 Sa f'ọwọ fun aṣọ rẹ pọ ninu omi pẹlu SURF**

Ma șopo gboo, ma șopo run un. Bi awọn aṣọ na ba riri gidigidi, fi wọn silẹ ki nwọn rẹ daradara ninu hiho SURF na fun wakati kan ni akọkọ.

**2 Wo o bi gbogbo rẹ ti mọ gaara si**

Ati funfun ati alawọ orișiriși ni yio jade ninu hiho SURF na pẹlu mimọ lauluu—MIMỌ GAARA.

**3 Wa a le ri bi eeri ti nyọ jade**



Bojuwo omi dudu na ki o fi o daa nu. Bẹni—agbara idan SURF ti yọ gbogbo eeri jade: awọn aṣọ rẹ si mọ ju ti atijọ lọ.







## Imọran atata fun ara Ọffa

JỌWỌ gba mi laye diẹ ninu iwe "Irohin Yoruba lati ba awọn ọmọ Ọffa sọrọ diẹ lori ibo Gbogbogboo ti nwọn fẹ di yan awọn aṣoju Igbimọ-Nla Apapọ Ijọba Naijiria ni ipari ọdun yi, ọrọ mi na nipe mo bẹ gbogbo awọn ọmọ Ọffa ni 'bikibi ti nwọn lewa pe awọn aṣoju ti Ẹgbẹ Afẹnifẹre ba yan s'ode gẹgẹbi aṣoju ilu Ọffa ninu Igbimọ na ni ki nwọn dibo fun wọ'le

Ẹnikẹni ti o ba fẹ rere ilu Ọffa, alalẹ Ọffa yio fẹ rere fun oluwarẹ, șugbọn ẹniti ko ba fẹ rere Ọffa, alalẹ Ọffa ko ni fẹ rere fun oluwarẹ na o. Amin. Gbogbo ẹnyin ọmọ Ọffa ati Ilọrin ati agbegbe rẹ aṣoju Ẹgbẹ Olọpẹ ni ki ẹ dibo fun o ki Oluwa Olodumare o ran gbogbo wa l'ọwọ ki o si gbe Ẹgbẹ Afẹnifẹre leke awọn ọta o. Amin.

Mo dupẹ aye ti Olotu gba mi o.

Emi ni,
S. M. ADEDIBU.

Igbẹtti, Ilọrin.

## Ilu Osogun nfẹ omi

JỌWỌ Olotu iwe "Irohin Yoruba" gba mi laye diẹ lati ke si Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria pe ki awọn fun wa lomi ni ilu yi nipa gbigbẹ kanga fun wa. O ti to oșu mẹjọ nisisiyi ti a ko ti ri omi ni ilu na mọ, eyi si mu ki ọpọlọpọ kuro ni'lu t'ọmọ-t'ọmọ lọ si Ibadan.

Enia iba ti pọ ni ilu na nitori nwọn nfẹ lati wa da'ko koko sibẹ șugbọn aiṣomi mimu yi ko jẹ nitorina mo bẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ki nwọn jọwọ tete ba ni ri si omi yi o

Emi ni,
ỌJỌ OGUN (Ẹlẹrọ)

Ile Amọrẹ Osogun,
Ọyọ.

## A nreti o, Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun

INU awa ara ilu Idọgọ dun pupọ ni ọjọ kẹtala oșu kejila ọdun ti o kọja yi nigbati a gbọ ikede Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun ninu ẹrọ redio pe awọn yio tun afara Odo-Iyewa ti o wa ni Idọgọ șe ninu ọdun yi. A dupẹ pupọ l'ọwọ Oloye E. A. A. Fadairo, ẹniti o ba wa gbe ọran na siwaju Ijọba na, a si tun dupẹ lọwọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun paapa fun ifẹnisọkan.

A dupẹ o, a si nreti o.

Emi ni,
D. D. Arojojoye.

Railway Station,
Idọgọ.

## Ọkunrin kan ṣa ekeji rẹ p: lati oju-orun

IJẸBU-ODE.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni nwọn bẹrẹ ẹjọ ọdaran-apania kan, Sule Odunẹjọ, eni ọdun marundinlogoji ni Kotu Ganran Ijẹbu-Ode niwaju Adajọ-Agba W. H. Irwin ti awon ọlọpa sun ni esun pe, o ṣa enikan ti nje Jimo Kasunmu, alapata, eni ogun ọdun ti nwọn jijọ ngbe inu 'yara kanna pa lati oju orun.

Ọga-ọlọpa Samuel Oludairo ti o mba ọdaran na ṣẹjọ sọ fun Adajọ pe, ọdaran yi pelu eniti oku na jijọ ngbe inu 'yara kanna ni ni 4, Ituna Street, Ijẹbu-Ode, o ni, ni arin ọse na ni eniti o ku yi gba owo-eesu kan jọ kakiri bi iṣe re, ọdaran yi si ro pe inu 'yara ti nwọn jijọ ngbe ni o gbe awọn owo na pamọ si ni o ba fi mu ada ti o si ṣa a pa lati oju-orun.

Ẹnikan ni o kigbe wa sọ fun awọn ọlọpa, ni awọn ọlọpa ba da lọ si ibẹ pelu eniti o wa sọ fun wọn, nwọn si ba ilẹkun iyara na ni titigbọnin-gbọnin, awọn ọlọpa ba fi agbara ṣi ilẹkun wọ ile, nwọn si ba eniti nwọn ṣa pa na ninu agbara ẹjẹ ati ọdaran na ti o la oju rẹ mejeji silẹ ti o pe oti sun lọ. Adajọ si ti yẹ ọjọ ẹjọ re si ọjọ miran.

## Ọdẹyẹmi gbe Adebọla niyawo

NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kini oṣu kini ọdun yi ni Joseph Adewọye Ọdẹyẹmi gbe Omidan Mary Adebọla ni iyawo. Irohin ko to amojuba ni ẹyẹ igbeyawo na, awọn ẹbi t'ọkọ-t'aya na wabiwọsi owo l'ọjọ na, nwọn fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni R. O. Afọlabi, A. Afọlabi, A. Fasheyiro, P. Ọdẹdiran, Ayọ, T. Adeniran, A. O. Oyedele ati awọn Omidan D. O. Omotọshọ, J. A. Ayanbisi, M. Ọdẹdiran ati V. Ọlanipẹkun.

Ki Olorun fi ọmọ rere ta t'ọkọ t'aya na lọrẹ o. Amin.



# Ẹhanna Erin kan doju ija kọ Dọkita Nkrumah

MYSORE.

NI ọjọ'Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni ẹhanna Erin kan ti o roro pupọ pakuru mọ Dọkita Nkrumah, Alakoso Ijọba Ghana ninu moto ti on ati ọde atamatase kan, Maharajah ilu Mysore wa nigbati o ngmu Alakoso Ijọba Ghana na lọ woran awọn ẹranko ninu igbo erin Bandipur, ni Mysore India, lẹsẹkẹsẹ ni Maharaja na yin ibọn ilewọ kan lu erin na latari lati fi dẹru ba a, erin na si fi irora fọn kikan-kikan o si salọ lẹsẹkẹsẹ sinu igbo ramirami. Ẹkun ti o tun fẹ yinbọn fun lẹhin eyi salọ mọ ọ lowọ.




# Ẹgbẹ Kerubu ati Serafu Agelu Jerusalem ṣe Ajọdun Isọdọmọ

ADO-AWAYE.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kokanlelogun oṣu kejila ọdun ti o kọja yi ni Ijọ Ẹgbẹ Mimọ Kerubu ati Serafu, Agelu Jerusalem (Ilu Ogo) ṣe Ajọdun Isọdọmọ (Ikore). Nigbati Ajọdun na ti ku ọtunla ni awọn aṣoju Ẹgbẹ Serafu kakiri gbogbo ilu Oke-Ogun bi Ibarapa, Shaki, Okeho, Irẹpọ, Imẹkọ, Ibariba ati bẹẹ bẹẹ lọ ti peju sibẹ. Nigbati ọjọ Ajọdun na si ku ọla, nwọn ṣe ipade pataki kan fun eto ilọsiwaju Ẹgbẹ Kerubu ati Serafu gbogbo ti o wa ni Oke-Ogun, Baba wọn, 'Woli Agbo-Jesu' ni o fi adura pari ipade na.

Lati aro kutu-hai ni awọn Woli ti bẹrẹ si kede f'awọn enia pe ki nwọn tete wa si Ile Adura fun Ajọdun na, lẹhin ti nwọn jẹun tan ni agogo mẹsan owurọ, nwọn bẹrẹ Isin Ipade Ajọdun na ni agogo mẹwa, Aposteli J. A. Olagunju, Alaga Igbimọ Ajọ Oke-Ogun ni o wasu, "Woli Agbọ-Jesu" si fi ariya nla mu ori gbogbo enia wu. O ni ijọ ni Dafidi jo ni iwaju Apoti-Ẹri Oluwa ti o fi di Ologo nla.

Oniwasu na yan ẹsẹ wura rẹ lati inu Eksodu ori 23 ẹsẹ 15 de 25, ṣugbọn eyiti o mu ẹko pataki ti o fi ko awọn Ijọ jade ninu rẹ ni ẹsẹ 19, ti o ka bayi pe "Iwọ ko gbọdọ bọ ọmọ ewurẹ ninu wara iya rẹ". Gbogbo Ijọ si gbadun ẹkọ rẹ bi ki o ma dakẹ mọ ni. Oniwasu na si mẹnukan ore Ọlọrun lori Ijọ yi ati ọna ti Oluwa fi tẹ Ilu Agelu yi do lati ọwọ Woli Akintobi 'Agbọ-Jesu" lati inu ọdun 1953. Awọn agbẹ ati olukuluku oṣiṣẹ si mu aayo ohun iṣura iṣẹ ọwọ wọn wa ṣọpẹ f'Oluwa gẹgẹbi apẹrẹ ti Abel fi lelẹ.

Woli S. A. Abegunde, Akọwe Ẹgbẹ Ijọ ni o ṣe eto gbogbo, bi ijoko ajọdun na ṣe wa ni irọrun titi ti nwọn fi pari ajọdun na. Baba Woli Abegunde na, Ogbeni Joseph Abegunde wa si ipade ajọdun lati ilu rẹ ati fun ibẹwo ọmọ rẹ na. Ẹgbẹ Imọlẹ ati Ẹgbẹ Akọrin bukun isin ajọdun na nipa fifi ilu, orin ati ijo yin Oluwa. Ajọdun Isọdọmọ (Ikore) na dun ju gbogbo eyiti nwọn ti nṣe lati ẹhinwa lọ. Aṣeyi-ṣamọdun o.

Ẹ MA A
POLOWO ỌJA
NYIN SINU IWE
Irohin
Yoruba



# Akiyesi awọn Awo-Irawọ nipa Ọjọ-Ibi

AWỌN nkan wọnyi ni yio sẹlẹ larin ọsẹ yi (Jan. 18th—24th) si awọn ti ọjọbi wọn ba bọ si arin awọn ọjọ osu ti a daruko si isalẹ wọnyi.

## CAPRICORN

DEC. 21ST—JAN 19TH)

Bi o ba ti ṣe wahala nipa ibatan rẹ kan ti o sunmọ ẹ, wa a ri pe awọn iṣoro rẹ yio yanju nipari ọsẹ yi. Nipa ọran awọn ẹbi pẹlu, asiko lati tun nkanṣe niyi ati lati ṣe ijiroro pupọ. Nipasẹ ohun ti o ba jẹmọ owo (money) wa a si ma a wa laye dada, wa a si ni awọn ọrẹ ti nwọn wulo.

## AQUARIUS

(JAN. 20TH—FEB 18TH)

Wa a mọ pe bi o ba fẹ dunnu o ni lati ṣe awọn ayipada kan ninu awọn ibatan. Ko ni le ṣe e ṣe mọ lati da awọn ipinnu duro tabi lati ma a fi ara da ipo iṣoro kan lo. Nipasẹ ti owo, ọsẹ bukata nla ni ṣugbọn wa a ni ilosiwaju asiki pẹlu.

## PISCES

(FEB 19TH—MAR. 20TH)

Ṣe ayipada kan ninu iṣẹ rẹ ojojumọ ti yio mu irọrun wa diẹ. Nipasẹ okun ti o jẹmọ owo, aseko rere mbọ, iwọ a si gburo rere nipari ọsẹ yi. Maṣe tun ṣe afowọfa mọ titi oṣu diẹ t'ombo, bi o ti wu ki o ri.

## ARIES

(MAR 21ST—APL. 20TH)

Ni pẹlẹ-pẹlẹ ṣugbọn daju-daju wa a da iṣẹ kan silẹ ti yio gba aseko diẹ ki o to gberu. Okowo yio wa lati ọdọ alajumọsepọ tabi olu-ranlọwọ kan ti o fi ọkan tan ẹ. Igbesi aiye rẹ le wa segesege, nipa bayi ẹru si le ba ọrẹ rẹ titun kan pupọ.

## TAURUS

APL. 21ST—MAY 20TH)

Awọn ayipada ti o jẹmọ igbesi-aiye rẹ ni ile rẹ ati opo agbekẹle rẹ nsunmọra gan an lati sẹlẹ. Bi ọsẹ yi ba fẹ pari, wa a ri awọn ami igbati awọn ayipada na ni lati sẹlẹ. Nitootọ o le ma a ro wipe awọn eto titun, ma ti i gbe awọn ero rẹ jade titi ti awọn ẹlomiran yio fi gbe ero tiwọn jade.

## GEMINI

(MAY 21ST—JUNE 20TH)

Awọn edeaiyede ni ibi-pataki ibiṣe rẹ fẹrẹ kuro. Titi ti nwọn a fi pari, lootọ wa a ri pe o nṣiṣẹ a ṣe le. Ko yẹ lati ṣe wahala nipa owo: gbogbo ohun ti o ba se nwọn yio sanwo rẹ fun e dada.

## CANCER

(JUNE 21ST—JULY 20TH)

Iṣro ti o wa fun ẹniti o sunmọ ẹ pupọjulọ ti o si sọwọn fun ẹ julọ nle si i ni. Lẹsẹkẹsẹ wa a mọ pe o ni awọn ọrẹ atata, nwọn a si sa gbogbo agbara wọn lati ran ẹ lọwọ. Atunṣe iṣẹ tọ, bi o ba ni ireti lati ni owo laipẹ.

## LEO

(JULY 21ST—AUG. 21ST)

O wa nde aye ipẹkun edeaiyede ti o ti wa fun ẹ tipẹtipẹ. Bi o ba duro lori idi (ẹtọ) tirẹ, a dara fun e gan an ki o to to oṣu diẹ. Nipa igbesi aiye tirẹ paapa awọn idiwọ ndinku, wa a si ri ọna gba bọ ninu idiwọ na.

## VIRGO

(AUG. 22ND—SEP. 22ND)

Wa a ri pe iṣoro ni o jẹ fun ẹ lati siṣẹ rẹ ni aseko ti iṣẹ rẹ gba. Maṣe fikun awọn iṣoro rẹ nipa rinrin awọn ilinajo ti ko tọ tabi nipa dide ara rẹ nigbekun lori ọran awọn ẹbi. Ọrẹ ti yio dunmọ ẹ 'niyi larin irẹpọ ọrẹ: o nfi pẹlẹ-pẹlẹ ṣe irẹpọ pataki kan.

## LIBRA

(SEPT. 23RD—OCT. 23RD)

Bi ọran ile kan ba ti sẹlẹ, o ni lati ro nipa rẹ dada ninu ọsẹ tombọ. Ko yẹ ki o kanju sa o; ọran ile yi le gba oṣu diẹ ki o to bẹsile. Ohun titun kan ti wa a nifẹ si ati irẹpọ titun kan ti o fẹ ati ti yio ba igbesi-aiye rẹ mu, nwọn mbọ pẹlẹ-pẹlẹ.

## SCORPIO

(OCT. 24TH—NOV. 22ND

O le wa ninu iṣoro kan lori ọran iṣẹ agbaṣe pataki titun kan. O dabi ẹnipe opolopo owo fẹ wọle fun ẹ, ṣugbọn o mu inira dani. O le tọ lati ṣe ayipada ninu ohun afokantẹ ile rẹ tabi iṣesi lo igbesi aiye rẹ ki ọdun yi to pari.

## SAGITARIUS

(NOV. 23RD—DEC. 20TH)

Lootọ aiye tubọ ṣoro fun ẹ si ni ju ti atẹhinwa lọ, boya inu rẹ yio dun ju ti akoko kanlọ. Wa wa mọ nisisiyi pe o wa de opin iriri igbesi aiye kan ati pe, o si bọ ninu inira kan. Ma a ṣe awọn eto titun lọ ṣugbọn ni pẹlẹpẹlẹ ati pẹlu ọgbọn-ewẹ ni ki o fi ma a ṣe wọn.

---

## ALỌ O? ALỌ!

Lati ọwọ J. Olurebi Williams Mushin.

1. Paminku egun ṣiwaju, atẹlenimaya olọkọ rẹ tẹle e, fusa ti Ṣango yo lẹhin wọn, bi o kanran ki nwọn ya kuro lọna fun Ṣango, olọkọ rẹ ni "nṣo, nṣo, nṣo ko si ohun ti Olubambi onina-lẹnu fẹ fi wa ṣe! Mẹta ni a npa a, mẹta ni a nja a, bi a ba pe "mọ ọ" ọmọran a mọ ọ?
2. Ọsingin iyawo ọlọrun-segi, o nfẹ kọ ọkọ rẹ ṣugbọn ti Iwọfa ọkọ ni ko jẹki o le kọ o. Tani Iwọfa na?
3. Ṣo-ṣo-ṣo firu balẹ, ti ko ba fi'ru balẹ ina a ṣẹ.
4. Bintin losan, baara-baara loru.
5. Ohun ti aja mọ odu (kokoro orun aja) rẹ ko mọ o.
6. Ẹlẹkun ḍakẹ, alagbasun ko dakẹ.

## ITUMỌ ALỌ

1. Ekini, ọmọlanke, ekeji ọlọmọlanke, eketa Bọ'lẹkaja.
2. Owo ni Iwọfa na.
3. Moto ti o nko epo-moto.
4. Ina.
5. Ada ni aja, eeku rẹ ni odu, nitori ti nwọn ba ngbọn ada lagbede nwọn ko ni i gbọn eeku rẹ pẹlu.
6. kanrinkan-iwẹ.

## Adajọ ni ki ọlọti bọlugi fi £25 tanran

EBUTE-MẸTTA.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi ni Ogbẹni Ayọ Richards, Adajọ Kotu kekere kan l'Ebute Mẹtta ni ki Johnson Etete, ọdaran kan ti awọn ọlọpa mba rojọ pe nwọn ka igo ọti "fidigbogi" mẹsan mọ l'ọwọ ninu 'yara rẹ ni ọjọ ti o nṣeyẹ isinku baba rẹ lọ san ponun mẹdọgbọn owo itanran ẹsẹ na.

Nigbati ọdaran na nṣe inawo oku baba rẹ ti o ṣẹṣẹ ku ti awọn ọrẹ, alabakẹdun ati awọn mo-gbọ mo-wa nwọ wa nki i ni ọdaran na ba wọ'le gbe ọti bọlugi na ṣe wọn lalejo, lẹnu alejo ṣiṣe yi ni awọn ọlọpa wọ'le de, ti nwọn ba ọti l'ọwọ rẹ, nigbati nwọn si yẹ 'yara rẹ wo ni nwọn ba igo mẹsan miran ki o to di ọran kotu.

## Ọdunlami gbe Abikẹ niyawo

NGURU.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni Ogbẹni T. Ade. Ọdunlami gbe Omidan Abikẹ Akintọla ni iyawo ni Ṣọọṣi Ijọ Kerubu ati Serafu Eka Nguru ni nwọn ti ṣe igbeyawo na, Ogbẹni J. O. Ọlatunji ni o ṣe iwasu, o si yan ẹsẹ iwasu rẹ ninu Efesu ori 5 ẹsẹ 22 de 28 pẹlu itan kukuru kan ti o mu ọgbọn ati ẹkọ dani pupọ fun t'ọkọ-t'aya na.

Fun ti ijo ati orin, igbeyawo wu ẹnikẹni l'ọjọ na, niti onjẹ, irohin ko to afojuba ni. Diẹ ninu awọn alabaṣeyẹ ọjọ na ni Woli M. O. Adenibi, Ogbẹni E. A. Akinṣiku, L. Ade. Johnson, Pa Adio Aiyesimoju, Adetọna, Alagba Etutu, A. M. Durojaiye, M. O. Latidoye, Iyaafin P. A. Adewole ati Iyaafin William.

Ọlọrun a fi'rẹ kari o. Amin.

*Lebẹli yi jẹrisi*




OJULOWO

DUTCH WAX PRINTS

AWỌ TO DARA JULỌ ATI OHUN ELO TO DARA JULỌ

J311Y







# Ọrọ awọn Akewi Yoruba



### Lati ọwọ Ṣọla Adekanmbi,
### 1, Wellington Square Oxford England

MO kọ Ewi yi lori "Ikini". Inu mi yio si dun bi ẹ ba le ba mi tẹ ẹ sinu "Irohin Yoruba" oloyinmọmọ.

Akoko to ti a ni lati ma a yọ ẹwa inu ede Yoruba han araiye. Boya eyi ti mo kọ yi yio wu awọn ọmọ Yoruba miran lori lati le tun gbiyanju kọ Ewi (Poem) Yoruba ti o dara kan. Nipa bayi, ọwọ ati ẹwa ede na yio ma a gbilẹ de dara kan. Nipa bayi, owọ ati ẹwa ede na yio ma a gbilẹ de ibi pe yio gba orilẹ wa kan.

1. "Ago onile o!" li alejo nwi,
Ti onile na o si jẹ ẹ ni "Ago ya";
A ki i ragiri wọle laikago,
Ki o ma ba di ogun ẹtiri.

2. Bi ewurẹ wọle laikago, a di mimu so,
Bi agutan wọle laikago a gba okun s'ọrun,
Bi ọmọluwabi wọle ti ko kago,
Onile a di igba ọtako le e lori bi o ti yẹ.

3. Onile, mo bọde ki ngbo wọle,
Agun-ala, mo bode oṣu,
Aja oṣupa mo bode lọna ọrun
Ti gbogbo wa jọ nlọ.

4. Eni duro ẹ ku iduro;
Eni joko ẹ ku ikalẹ;
Ero ọrere ẹ ku agbọ-dide
Gbogbo nyin ni mo ki, ọmọ 'ku ootu, oojire'.

5. Bi ojumọ mọ— n'ile Ajerọ n' ile Alara—
Ọmọde ile a ni, "ẹ jire";
Alagba ti a nki a fi oyaya fesi
Pe, "ku owurọ, o ko ji bi? oni a san ọ, ọmọ"

6. Bi ọmọde ba ma ki ẹni iwaju,
A ni, "ki ẹ pẹ, baba";
Ẹniti a nki na, a fesi agba
Pe, "Kare, gbere, ọ ku ọmọ!"

7. Bi enia ṣe nkan ara bi o jagun-molu,
Tabi o si hu iwa akin kan ni:
"O ṣeun, o kare, o ku tọ" li a ki eleyini,
Fun ohun ẹwa on iṣiri bayi ti a le fi ṣogo.

8. "Pẹlẹ, ku iroju, ku ifarada":
Li a ṣe ẹni fi ori gbun, tabi t'o padanu,
Tabi iru ẹni ikamu bawon ni
Ti o gba ọgbẹ ọkan tabi ti ara.

9. Ẹni ti njade lọ nile fun sa kan,
A ki ara ile pe "o dabọ".
Awọn ti o nfi sile na, a ni "o rewa,
"Ma pẹ, o dabọ, yara lọ".

10. Bi o ṣe ti ẹniti nlọ si ajo pipe,
A ni 'ara ile, odigboṣe!"
Awọn na, a ni "o digba, ona re,
"A o pade l'ayọ, a ko ni fọn ire."

11. Bi a ba ti ri ara ẹni pẹ,
'Ẹ ku ati (Jọ)", li a nki ara
"Alafia kọ bi?" li a bere
Ara le tabi ko le."

12. Kiki ti alaboyun gba ẹrọ,
Epe ko tọ si ẹni di 'wọ di 'ṣe s'ikun,
A ni, 'O ku iṣẹra, afon a gbo ki o to wọ,
"A o gbohun iya, a o si gbohun ọmọ".

13. "Mo k'ota, mo k' ope",
Li a ṣe alayo meji ti nta,
Eyiti o gbowọ a si dahun pe,
"Ọta nje, ope ko gbọdọ fọhun", bẹni dandan

14. "Oku gboro o!" lẹnu lẹẹ,
Liaki onidiri, oniṣona on ahunṣọ;
Eniti a ki na, a si dahun pe,
"Ọya a ya". Ṣe ẹ li a ṣe nki ni.

**KOI TI PARI**

*Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"*







Alapata ti o darajulo nlo si Banki ti o darajulo.

BARCLAYS BANK D.C.O.

Iwọ, paapa, le bẹrẹsi fi owo rẹ pamọ sibẹ loni.

Bi o ba fẹ lati gbajumọ

Ra BICYCLE

Siga ti o l'okiki ni Naijiria





# Awọn ọmọ Awaiyewaşepe şe iranti bab.ı wọn

EKO.

NI ọjọ Ọjọbọ ti işe ọjọ kẹdogbon oşu kejila ọdun ti o koja yi—ọjọ Ọdun Keresimesi ni awọn ọmọ Alhaji James Asani Disu, Z.Q. ti apele oruko rẹ njẹ "Alhaji Awaiyewaşere" şe iranti ologbe baba wọn na ti o ti lọ jẹpe Ọlorun lati ọdun kẹjọ sẹhin. Alhaji-Imam-Deen J. G. Bakare Ọtun ni o şe akanşe isin fun ologbe na, awọn Imam Dauda ti Mọşalaşi Ọba Eko ati ti Mọşalaşi Ebute-Ero ati ti Agoro si ran an lọwọ. Nwọn sọ ọpọlọpọ ọrọ iwuri nipa ologbe na, bi o ti şe jẹ olufọkansin, ọlọyaya, alapara ati ọlawọ si ni igba aiye rẹ.

Awọn ọmọ ologbe na, paapa Ọgbẹni Y. Ayinla Disu (Bibman) daudu rẹ, nawo nara., nwọn fi orişirişi onjẹ adidun te awọn bi ẹdẹgbẹta (500) enia, alabaşeye ọjọ na lọrun titi ti ilẹ fi şu. Irohin ko to afojuba ni ẹyẹ ọjọ na.



OLOGBE ALHADJI AWAIYEWAŞERE, Z.Q.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn ọmọ-oloku na ti o pe sibẹ ni awọn Ọgbẹni Muyinu Disu, Abudu Ganiyu Adebayọ Disu, Shakiru Akinọla Disu, Muniru Disu, Moroof Disu; awọn Omidan Muniratu Giwa, Raliatu Kasunmu, Thiryibat Disu, Kudiratu Smith ati Jaodatu Disu.

Ki Oluwa şe ikẹ oku na, ki O si tun ẹhin rẹ şe.

## Akọwe-agba Ẹka Ẹgbẹ Alakukọ Opobo di ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre

OPOBO.

NI ọjọ 'Ru ti işe ọjọ kẹrinla oşu yi ni Ọgbẹni A. O. I. Idounam, ti o ti wa ni aye Akọwe-agba ti o ngbẹnusọ fun ẹka Ẹgbẹ Alakukọ Opobo tẹlẹri fi Ẹgbẹ na silẹ ti o si wọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group), Ninu iwe ifẹgbẹsilẹ ti Ọgbẹni Idounam fi ranşẹ si akọwe Ẹgbẹ Alakukọ, o şe alaye pe on fi Ẹgbẹ Alakukọ na silẹ nitoripe, "o lodi si imọran yiya awọn ilu Kalaba, Ogoja ati awọn ilu Etido sọtọ."


ỌLỌGBỌN ONIṢOWO NGUN RALEIGH

Pẹlu Raleigh onisọwo yi le ko ọpọlọpọ nkan tita. Ko gb'asiko rara, pẹlu irọrun ni yio ma gun u lat'abule d'abule. Ọpọlọpọ ni yio ma taja fun lojojumọ. Nipa bẹ yio ma pa'wo pupọ.

O GBỌDỌ *gun Raleigh*

GBOGBO IRIN KẸKẸ

RALEIGH

LORỌ



# ORIN MIMỌ TI A FẸRAN

**Lati Ọwọ E. Alabi Thompson**

"E GBẸKẸLE Oluwa titi: nitori Oluwa Jehovah ti apata aiyeraiye"—Isaiah 26 ẹsẹ 4.

1. Apata Aiyeraiye
Ṣe ibi isadi mi
Jẹki omi on ẹjẹ
T'o ṣan lati iha rẹ
Ṣe iwosan f'ẹṣẹ mi
K'o si sọ mi di mimọ.

2. Ki ṣe iṣẹ ọwọ mi
L'o le mu ofin rẹ ṣẹ
B'itara mi ko ṣarẹ
T'omijẹ mi nṣan titi
Nwọn ko to ṣetu f'ẹṣẹ
Wọ nikan lo le gbala.

3. K'o sohun ti mo mu wa
Mo rọ mọ agbelebu
Mo wa k'o d'aṣọ bo mi
Mo nwa o fun iranwọ
Mo wa sib'Orisun ni
Wẹ mi Olugbala mi.

4. Gbati ẹmi mi ba nlọ
T'iku ba p'oju mi de
T'mba lọ s'aiye aimọ
Ti mo ri Ọ n'itẹ rẹ.
Apata Aiyeraiye
Ṣe ibi Isadi mi.

**ITAN ORIN NA**

Itan orin yi fi ohun iyanu kan han wa, eyiti o mu wa gbagbọ wipe, ẹmi ijọsin tabi ẹmi ifọkansin ko kan wipe lagbaja mọ iwe, tabi o l'oye.

Ọgbẹni Augustus Montague Topbady ti o kọ orin oke yi jẹ ọpe gidigidi ninu imọ Ọlọrun, bi o tilẹ jẹ pe, o gb'oye, o si ni ọgbọn iwe ti o ye kooro. O ba ọkunrin ẹniti orukọ rẹ njẹ James Morris pade, James jẹ agbẹ. Nipa ifi ọrọ we ọrọ ninu Bibeli ni Ọgbẹni Topbady ti ri iyipada ọkan. O si gbiyanju lati jẹ olufọkansin.

Nigbati Topbady darugbo ti o si ri iriri wipe iku ko ni I pẹ de lati oye igbagbọ ati ẹmi ifọkansin han. O gbiyanju lati kọ orin oke yi lori akete iku, eyiti o si di lilo kakiri ilẹ igbagbọ.




FUN AGBARA ATI OKUN




Njẹ irewẹsi, arẹ ati aisan ma nṣe ọ l'ekọkan? Bi o ba ribe, eyi ni ohun ti o nilati ṣe. Mu Egbogi Phosferine Tonic Wine lojojumọ. O nmu ki ọkunrin tobi ki o si sigbọnlẹ. O nfun obinrin ni agbara ati ilera. Yio fun awọn iṣan ara rẹ li agbara, eyi yio si jẹki o sun gbadun ki si ji didi pẹlu idunnu. Ra Egbogi Phosferine Tonic Wine yi *l'owo gangan*. Egbogi atata ni eyi

**PHOSFERINE TONIC WINE**

*agbo ti o gbadun . . .*
*mejetitun nla – yio se o ni ire.*


Printed and published by the Amalgamated Press (of Nigeria) Ltd. 5/7 Apongbon Street Lagos (Editorial and Advert offices) Telephone 23675 Fun owo "Irohin Yoruba" odun kan: Eko—sile mejo ati kobo mejo (8s 8d.) Ilu miran ni Naijiria ati Oke-Okun—sile metala (13s.) Ololu E M. Ademuyiwa, 9, Chapel Street Lagos

# Ọlọla Adetokunbọ Ademọla gba Ọpa Aṣẹ Idajọ

*Lati oju ewe'kini*

tokunbo paapa wa yan awọn Oloye F. R. A. Williams ati H. O. Davies ni ọkọọkan si aye oye wọn ninu Kotu bayi pe: "Inu Ọlọlajulọ Ọba'birin Gẹẹsi ti dun si i gẹgẹbi ọkan ninu awọn Iriju -Amofin rẹ, nitorina gẹgẹbi aye oye ti Ọba'birin na fi da o lọla yi, bọ si ipo oye na, ki o si joko ni Kotu larin awọn Amofin". Nigbati o fi ẹnikọọkan wọn si aye oye yi tan ni olukuluku ba bẹrẹsi sọrọ aponle nipa aṣeye na.

Ninu ipade aṣeye ti nwọn ṣe fun Ọlọla Adetokunbọ Ademola, Adajọ-Agba Apapọ Ijọba Najiria ati awọn Oloye F. R. A. Williams, Minista Alamojuto Iṣẹ Idajọ-ododo ati Ohun Iṣura Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ati Oloye H. O. Davies, Gbajumọ-agbẹjọro kan li Eko, ọpọlọpọ awọn enia patakipataki, awọn Minista, awọn Ijoye, awọn Ọlọla ati awọn Ẹgbẹ Loya ti nwọn to ninu ẹwu oye wọn ni o pẹju ṣọṣọ sibẹ ni ọjọ na, eyẹ na si dun de ibiti o nyẹ enia de.

## Ọmọ ti nwọn bẹ lori

*Lati oju ewe kini*

Kẹhinde Sofọla ti sọ fun Adajọ, pe on yio ṣe agbẹjọro wọn.

Ọlọpa'nu Stephen Ajayi ti o wa lati Ibadan ti o ṣe iwadi awọn ọdaran yi si tun wa lẹnu pe o nwa awọn ọkunrin meji kan kiri ti nwọn le mọ nipa ọran yi. Obirin kan si tun wa ni itimọle ọlọpa Mushin nisisiyi, ti o ngbe Omididun Street l'Eko, ti nwọn lero pe on paapa yio mọ nipa ọran na.


## IDIJE YORUBA FUN £300

First entry 2/6d. Each additional entry 1/- only.
1st prize £150; 2nd £75; 3rd £50. Consolation £25.
Closing date 2nd February, 1959. Result 9th February 1959.

AWON ORUKỌ YORUBA MẸSAN

| | | |
|---|---|---|
| 1. ADE — — PO | 4. A — ON — A | 7. SOFO — — |
| 2. F — TUGA | 5. ADEDO — — N | 8. AJI — O — — |
| 3. JAIYEO — — | 6. ṢO — OLU | 9. FEYIS — — — |

Orukọ ati Ibugbe.........................................

..........................................Iye Owo ..........

Post your entries and money in Postal Orders to THE MANAGER, NEW INDUSTRIAL ENTERPRISE, P. O. BOX 11, IJẸBU-IGBO, NIGERIA.



